# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 557 TUESDAY MARCH 17, 1964 (2D)


## Awọn Ero Ọja Ṣe Ọkunrin Kan Jẹ Pa

ONITSHA :— Gbogbo ilu gọọjikan fun ariwo nigbati Ọkunrin kan Owen Olayia ẹni ọdun mẹfidialogbọn ti o nṣiṣẹ akọwe ninu mọto Armels tẹle awọn ọmọ ẹgbọn rẹ Obinrin ti awọn ero ọja si dide lojiji ti ciukuluku wọn bẹrẹ si fi ehin ge Olayia jẹ ti nwọn si pa bamubamu si arin Ọja ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi.

Ẹniti ọrọ na ṣoju rẹ fi ye O n i w e irohin wa wipe, ẹgbẹni Olayia ṣẹṣẹ de lati ibiṣẹ ni, ninu mọto rẹ, o si gbe mọto na si ẹgbẹ kan ni arin Ọja, o lọ wo awọn ọmọ ẹgbọn rẹ ti nwọn wa ni Onitsha. Nigbati o ki awọn ọmọ na tan, o fun wọn ni Owo ati awọn nkan ti o ra lọ fun wọn, awọn ọmọ na si dupẹ lọwọ rẹ.

Nigbati o si fẹ maa lọ, ni awọn ọmọ na ba ti ilẹkun ile wọn, nwọn si sin in lọ si idi mọto rẹ. Ṣugbọn bi nwọn ti de arin ọja ti o ku diẹ ki nwọn de ibiti o gbe mọto si, ni awọn ero ọja ba dide si ọkunrin na, ti nwọn ... ninu bi nwọn ti nlu ni nwọn nho ge le,

O tun ṣe alaye pe, awọn ero Ọja lero po o lọ ji awọn ọmọ ti o tẹle lẹhin gbe, yio ko wọn kuro nilu ni, awọn ọmọ na si nkigbe pe aburo iya awọn ni, ṣugbọn awọn enia na ko gbọ, a fi igbati nwọn ge Ọkunrin na jẹ pa bamubamu.

Awọn ọlọpa ti gbe oku Ọkunrin na lọ si Ile-iwosan ṣugbọn ki awọn ọlọpa o to de gbogbo awọn enia na ti salọ, nwọn si fi oku rẹ silẹ nibẹ.

## Ẹgbẹ Alakukọ Sọ Pe:

# AKINTỌLA GUN OLOYE AWOLỌWỌ LỌBẸ LỌRUN

**IBADAN:— Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni ikede kan jade ninu Ile iṣẹ ti ngbenuṣe fun ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) wipe "ẹkun eke" ni awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ nsun nipa ẹsun ti nwọn fi kan ẹgbẹ Alakukọ wipe awọn ọmọ Ibo nikan ni nwọn fi sẹnu iṣẹ ninu ẹgbẹ na nwọn ki igb awọn ọmọ Yoruba.**

Ẹgbẹ na sọ wipe, Oloye Akintola gun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ l'ọbẹ lẹhin ọrun nigbati o nsọ nigbakan wipe awọn ọmọ Ijẹbu nikan ni Oloye Awolọwọ ngba si iṣẹ.

Ikede ti o jade ninu ile awọn ọmọ ẹgbẹ na tun bu ẹnu atẹ ba Oloye Akintọla ati Oloye Fani-Kayọde wipe, nwọn ko wadi iye awọn ọmọ Yoruba Ibo ati Hausa ti nwọn wa ni aiye Alaga ninu igbimọ Apapọ ẹgbẹ Alakukọ.

Ẹgbẹ na tun sọ si aju wipe ẹgbẹ Dẹmọ ti oloye Akintọla da silẹ, nigbati o ni wipe awọn enia ipinlẹ iwọ orun ko gba ẹgbẹ Ọlọmọkulunbu (U.P.P.) ko le jẹ idunnu awọn enia ipinlẹ na, nitoripe ẹgbẹ oṣelu tuntun ki awọn enia nfẹ.

Ẹgbẹ na ni, a s ọ d u n Ọrọ ni Oloye Akintọla nsọ nigbati o sọ wipe ẹgbẹ Dẹmọ na ni yio mu irẹpọ, isọkan ati ifaiya balẹ wa fun awọn enia Ipinlẹ na.

Ikede ẹgbẹ na tun tọka si awọn ohun ti nwọn pe ni "iwa agabagebe" ti oloye Akintọla ti nhun si awọn ẹgbẹ na nigbati awọn ti bẹrẹ si se ijọba ipinlẹ na lati ọkan bi ọdun kan ole osu die.

IWA IJAMBA

Ẹgbẹ na ni, ninu osu keje ọdun ti ọkọja yi, ni oloye Akintọla gba ọna "ẹburu" ati da ẹgbẹ U.P.P. pọ mọ ẹgbẹ Afẹnifẹre laiko jẹki ẹgbẹ Alakukọ mọ ero ati ete rẹ.

"Nigbati ẹgbẹ na gbọ ọrọ yi ti nwọn si wadi lọdọ oloye Akintọla oṣẹ kanlẹ



**Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ**

bamubamu wipe ọrọ na ko ri bẹ."

"Lẹhinna ni awọn ọmọ ẹgbẹ na si daa laba wipe nitori ifẹ ati iṣọkan ohun ilọsiwaju Ipinlẹ yi, ki ẹgbẹ N. C N C., U. P P. ati A. G. o jijọ ma a ṣe Ijọba, Oloye Akintọla kọ jalẹ, o ni ẹgbẹ A. G. yio dori ọmọ on kodo, On ko ṣepọ pẹlu ẹgbẹ Afẹnifẹre."

Ẹgbẹ na t u n ṣe alaye wipe, "nigbati Oloye Akintọla yio fi da ẹgbẹ Dẹmọ silẹ, on ati Oloye Fani-Kayọde ṣe eto labẹbẹ nwọn si pa ẹgbẹ U, P' P ati awọn Ọmọ Ile Igbimo Ipinlẹ Iwọ Orun ti iṣe ẹgbẹ Alakukọ bọdi ẹgbẹ itun laiko sọ ohunkohun fun awọn Ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre."

Ẹgbẹ na wa bere wipe "Ọna wo ni ifẹ, alafia, isọkan ati ilọsi w ju le gba de Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nigbati ọ pa gbogbo ẹgbẹ pọ'mọ ara wọn ti ẹ wa yọ ẹgbẹ Afẹnifẹre silẹ? Ọna wo ni isọkan na yio gba wọle?"

"Nigbati Owọ nyin ti tẹ owo tan, ẹ wa npe awọn Ọmọ Ile Igbimọ na ni Ọkọ-ọkan ṣẹhin lati pin Owo na. Iẹnin ti ẹ ti mu wọn ṣe ibura, imulẹ ati edekun. Njẹ Ọna ifẹ ati isọkan niyi?"

IYARAẸNI SỌTỌ

Ẹgbẹ na ni "ko si aṣepọ ninu ẹgbẹ ti ẹ da silẹ yi bi ko ṣe lati ya awọn eya kan si Ọtọ.

Ẹgbẹ na ni, "Gbogbo awọn ti poọkọ ori won ba ṣi oju silẹ, ti ko si dojude, yio mọ dajudaju wipe, ẹgbẹ iyaraẹnisọtọ ni ẹgbẹ Oselu ti ẹ da silẹ yi."

Ikede ẹgbẹ na tun sọpe, "Kini ero ọkan awọn ọmọ ẹgbẹ na lati sọ pe awọn enia ko gbọdọ ṣe ipade ode gbangba, lẹgbẹ ha ni, ẹniti yio ba jẹun gbọnin-gbọnin, o gbọdọ tilọkun gbọnin-gbọin".

ORI PPE

Ikede ẹgbẹ na ni, ko si ẹnikan ti ori rẹ pe ti osi jẹ olotitọ ati olododo enia ti ko mọ wipe, ẹgbẹ na ko wa isọkan awọn enia Ipinlẹ yi, bi nwọn ti se nlu agogo ẹnu kakiri sugbọn on ti awọn ọmọ ẹgbẹ na nja fun ri apo wọn nikan

Ṣugbọn awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti se ikede ni ana wipe, akoso Ijọba ipinlẹ iwọ orun Naijirira ti bọ si ọwọ wọn

Oloye Akin—Olugbade ti se kilọkilọ fun awọn Ọmọ ẹgbẹ Olomi ninu Ile Igbimọ Asọfin Apapọ Ijọba Naijiria, pe ki nwọn se pẹlẹ lati maa ba Oloye Akintọla lọpọ, o wa pari Ọrọ rẹ pe'

Pasan ti a 'fi na iyale, mbẹ laja iyawo, ki Oloye na to wi bayi tan, gbogbo Ile Igbimọ na lo ku si ẹrin ki alaga to fi Ọwọ lu tabili pẹpẹpẹ.

# Nję Iyi Si Tun Wa Lara Awa Ọmọ Yoruba

Lati ọwọ
**Maşekęganmi**

Mo fę fi ye nyin pe Ọpọlọpọ awa ti a jẹ ọmọ bibi ilę Yoruba ni a ko mọ bi iyi ara wa ti to lati igbati alaye ti da wa si aiye. Şugbọn nigbati Ọlaju bęrę yi ni a şęşę bęrę si mọ iyatọ larin awa Yoruba pęlu iran miran ti o wa yi wa ka.

Mo şę iranti ọjọ kan ti mo lọ si Ile-Ifę ti mo si gbiyanju lati lọ wo ile kan ti nwọn ko awọn ohun atijọ si lęhin ile Oni Ifę, larin Aafin.

Bi mo ti de ibę ni mo ba ara ilu Brazil kan ti on na wa lati wo ran, Bi o ti nlọ ni emi na tęle ti asi bęrę si fun oju wa lonję iya lęnu nla ni fun wa lati ri gbogbo nkan wọn yi, ti ojẹ wipe awọn ohun atijọ ti awọn baba nla wa ti şe silę ni wọn.

Bi mo ti fę ma bọ ni arakunrin yi ba pe mi pe, ki wa, o sisọ pe awọn ohun ti on ri yi fi han dajudaju pe Iran Yoruba jẹ iran nla ti osi niyi,

Were mo da lo hun pe, otitọ ni ọrọ ti o sọ, şugbọn lati jọ ni ati niyi. ki şişe asiko isisiyi mọ.

Bi mo ti sọ bę tan ni mo ba pa ęhin da ti mo si ba temi lọ. Şugbọn iru idahun ti mo fun ọkunrin na ya lęnu pupọ.

Bọya ęo sọ pe bi mo şe sọ pe ko si iyi lara Yoruba mu mi jębi lati sọbę.

Ngo se alaye fun niwaju idirę ti mo fi sọ iru ọrọ yi fun ara ilu okere ti kise Ọmọ ilę wa.

Se bi lai pe jọjọ ni Ọkan ninu awọn Onmọwe ilę wa ti se Ọmọ Yoruba kọ jade ti osi sọ wipe ko dun mọ on bi ase bi on si arin awa Yoruba.

Nitori pe Ọpọlọpọ awọn enia on ni saba ma pe on mi orisirisi orukọ alebu ti on ba ti sọrọ ti o fę otitọ lar n wọn.

Mo fę bęrę lọwọ ęnyin onkawe ni pe kini itumọ Yoruba ti a npe wa yi jẹ? kini itumọ Yoruba jẹ ninu awo sise tabi larin ęgbę isęlu ti anse yi?

Itumọ ti ngo fi ye yin ni pe, awa ni Iran ti Ima saba tete fi han loju aiye pe ohun ti Ọlọrun se fun wa ko tę wa lọrun tabi iran ti ndu lati le fi igberaga se aiye rę, ti asi saba ma se akiti yan lori awọn ohun aiye ju orilę ede yoku lọ.

Ọna ani kan jọpọn ti o ti wa larin wa tali ki gbogbo enia le mọ pe "Emi ni mo wa nibę" papọju larin wa, ti si saba ma fa wa sęhin.

Iru Iwa ti awa ti awa lode



**Ọba Awujalę Ijębu-Ode**

aiye isinyi hu buru ju ti awọn baba nla wa lọ ti o fi jẹ wipe wahala ti oti da silę fun wa. awa na mọ pe ipa wa ko le ka mọ rara.

A fę wa sọ pe, awa laju, asi tun gbọn ju awọn baba nla wa lọ şugbọn ti abafi oju inu woo omugọ nla ni ọlaju wa yi wa a da si wa iara

Mo fę ki ę şe akiyesi ọpọlọpọ awọn ọmọwe ti ojẹ ọmọ Yoruba bi nwọn şesọ aşa ilę wa di ti Oyinbo

Bi ati le ki ęlomiran ninu wọn pe. "Ęku arọ o, Ọ.bęni" ohun ti yio fi da ọ lohun ni "Good mor ing".

Iru aşa bayi jẹ ọna ti afi ba aşa işę dalę wa jẹ loju ọpọlọpọ awọn alejo.

Ohun miran ti o tun ba asa ilę wa jẹ ti ọwọ awọn ọmọwe ọmọbinrin ilę wa, ọpọlọpọ ninu wọn lo nlọ ra irun ayederu ti wọn yio fi de irun ori wọn mọlę, ti wọn yio fi nkan pa ete wọn ti wọn yio si tun ko atike maju pa oju wọn, bęsi ni asọ Yoruba ni wọn wọ si ara wọn.

Mo bere lọwọ nyin ęnyin onkawe mi nję asa Yoruba ni yi bi?

Bęni ti aba tun sọ pe ęnikan nlo yoruba, eyi yi ti fi han pe ęniti ansọrọ rę jẹ ọlọgbọn enia ati alai sododo

Iru ede bayi ko si larin Ibo tabi Hausa ati Isol o rara.

Asa wa nilę yoruba ni ye lori gidi ti osi ję ohun ti o jọ ni loju ni gbogbo aiye.

Eyiyi fi han wa ninu ọrọ kan ti ologbe Faguuwa tę jade ninu iwe irohin "The Service" ti ọjọ k ọkanlosu keta ọdun 1961.

Osọ wipe, Yoruba ni on asa gidi ti ojọ ni loju larin ilę Afrika.

Asa wa na si mu ọgbọn lọwọ ju ti awọ iran miran lo, asa yi nsi ma gbe wa ni yi nigba gbogbo.

Nitoripe ninu ọrọ yoruba lati le ri ọkę aimọye owe lo risirisi ti o ba awọn ọrọ ti afę sọ mo ręgi, lai fi ohun kan pe meji.

Iru owe ba wọnyi sọ wọn ninu ede gęesi tabi ede miran ni orilede Afrika.

Apejuwe ti ngo se ni pe ti nwọn ba fi ipo kan da ęnikan lọla tabi bi ęnikan ba bi ọmọ ti titun tabi ki ęnikan jare ęjọ, ohun ti Oyinbo yio fi kini wipe 'mo ki ọ".

Bi oba jẹ pe ọmọ ęnikan jalasi tabi ki baba rę ki oku tabi ki ewu nla wuu, ohun ti oloyinbo yio so ni pe 'mo ba ọ kędun" opa ri.

Sugbọn ninu ede ti Yoruba ni ati ri orisirisi ọrọ ti ọba ona kọkan mu ti ofi jẹ wipe ki se bi ati se le ki ęniti ọmọ re jalaisi ni ao ki ęniti baba rę ba ku.

Asa miran tl otun wa 'arin lę wa ni, ona ti angba sọ orukọ awọn ọmọ wa, bi ase wọ asọ ilę wa, bi ati se lu ilu ilę wa ati bi awọn obinrin wa se di irun wọn, jẹ ohun ti oye ki oju lowo ọmọ Yoruba wa iyatọ rę si ti iran miran

Oyę ki ama pe gbogbo awọn ohun ti ofa iyi wa fun ilę wa ni ati wa ọna lati parun eyiyi buru si i r a n yoruba.

Atun se akiyesi wipe, asa ilę wa ni pe ki ęnikan gęgę bi ọba ti yio ma jọba lori wa ipo yi ga larin ilę Yoruba pupọ.

Lasiko awọn Baba wa, ari wipe ipo ti wọn to awọn ọba wa si ga pupọ ju ti Igba yi lọ

Awọn ọba ma asiko yi ti di atę mọlę lesọ awọn onişelu wa.

Mo fę ki gbogbo wa, wa ọna ti afi le da awọn, iyi ati aşa wọn yi pada si ilę wa.

Ki şe igbati awọn ọmọ 'binrin wa ba kun ete wọn ti wọn si nku ekanna wọn ni a fi le ri ri iyi wa pada, bi ki şe pe ki afi agbajọ ọwọ wa şe işę fun ilọslwaju ilę wa.



ADESỌJI ADERĘMI

# IWE SI OLOTU

## Tani Nję Yęyęnatu ?

Olotu, jowo maşai gba mi laye diẹ ninu iwe Irohin gbedegbẹyọ lati le jẹ ki emi pelu olukowe ti o njẹ Yęyęnatu fi oju kan ara wa nitori ko si nkan meji ti mo şe fẹ mọ Sisi na ni wipe, imura si rẹ ninu aworan ti mo ma nri ọrọ rẹ ko ma nwu mi pupọ ati isọrọsi rẹ

Boya bi a ba jijọ foju kan ara wa bi o ti moun mi yi boya ọrọ wa le dogba pọ.

Mo dupẹ olotu oko oju ko ni şa nyin lesẹ o, aje de ara yio ma jẹ. Ao ni si ọrọ sọ o.

Emi ni
ARẸMU ERIN

Eko

arun ri

A tun so ẹgbe ọmọ Oduduwa di Olofin nitoripe ki awa ni ọkanna' lẹhin eyi nkọ? Ẹgbẹ oşelu miran ti tun jade. Ẹwa isọkan nkan ti ẹ o jẹ nile wa.

Eşe pupọ Olotu aşiri yio bo.

Emi ni,
LAISI AREMU

Ondo

## Gbogbo oju Ona Ibadan nfẹ atunşe

...na mi yio dun pupọ bi olotu ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe Irohin Imọle lati kesi Ijoba Ibile Ibadan pe, ki nwọn bi wa tun gbogbo oju ọna to wa ni Ibadan şe dada gbogbo rẹ ni o ni koto larin ti o si nba awọn moto ayọkẹlẹ nla jẹ ti nwọn ba jẹ si lojú.

Titi ti o lọ si ọna Isale-Osi ko dara to rara bẹ na ni eyini oke-Padi wa si Amunigun oju ọna na ti baje ti pe oju ona ti o ti oja Oje lọ si Oke Atipe na ti baje kiki koto ni oju ona ti de.

Mo daruko diẹ ninu awọn oju ọna ni, mo bẹ Ijoba Ibile Ibadan ki ẹ tete ba wa mojuto ni asiko yi ki ojo to de, nitoripe bi ojo ba de gbogbo oju ọna na ni o nbaję ti awọn awamọto ki fẹ ma gbe enia debẹ.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gbami olotu

Emi ni
T. A. TIJANI

Ibadan.

## Owo Oşu Awọn Ọlọpa

Olotu, ẹ jọwọ gba mi laye lati le sọro nipa ọrọ owo oşu awọn Olopa ilẹ Naijiria.

Ni asiko yi, gbogbo enia lo mọ pe gbogbo nkan ni o le ti o si nini lara, pataki fun awọn ọlọpa Ibile Iwo Orun Naijiria.

Ohun iyanu ni yio jẹ leti gbọ pe awọn ọlọpa ibilẹ ilu kankoni ti gba owo oşu wọn lati nka bi oşu meji sẹhin.

Nitorina mo bẹ lati rọ awọn Kansul ilu kọkan lati leripe nwọn san owo oşu awọn ọlọpa ni asiko ati pe awọn ọlọpa yi ni ọmọ ati iyawo ti nwọn ngbọ bukuta lori

Ẹ mu oju to ọrọ yi o.

S. YOBE BADEJỌ

Ijebu-ode

## Ẹgbe Titun Ko Lemu Irẹpọ wa

Olotu ẹgba mi ni aye lati so ẹdun ọkan mi jade fun araiye gbọ ninu iwe nyin ti nkọ wa ni ọgbọn ati oye,mo fi fẹ gbogbo enia mọ pe, ẹgbẹ tun ti nwọn şeşe de silẹ ni Iwo-Orun Naijiria ko le mu irẹpọ ati işokan wa rara si ariwa orile ẹde wa.

Nitoripe enia ko le mọ korira awọn kan ninu awọn orile -ede rẹ ki o wa sọ pe on nwa irẹpọ, ko le si irẹpọ rara a fi ki afa ara wa mọra

Lati igbati edeaiyede ti bẹ sarin ẹgbẹ Afẹnifẹre ni gbogbo nkan ko ti gbarawọn mọ Ipinle Iwọ-Orun kaka ki wọn pari rẹ ẹgbẹ miran ni

## Mo Ki Awọn Ẹgbẹ Arowoşọla ku Ọdun

Olotu, inu mi yio dun şeşe ti ẹ ba le gba mi laye lati le ki awọn ọmọ Ẹgbẹ 'Arowoşọla' - Aşa mba Eiyele şorẹ ẹiyẹle nyọ' ti ọmọ Ajaşe Epo pe nwọn ku inawo are ituau ọdun Aawẹ ti nwọn şe larin oşu ti o koja yi

Ayọ nla ni fun mi lati le ripe gbogbo ohun ti awọn ẹgbẹ na şe yẹẹ lai si mọdaru kankan.

Mo si tun ki ọdọmọkunrin ati awọn ọdomọbinrin inu ẹgbẹ ti o fi ijo to awọn ti o wa woran lọrun

Oyẹ ki nsi ti o ki,onilu ojọ na ti o fi orişirişi ilu rẹ dara ni ojọ na.

Mo dupe pupọ lọdọ nyin olotu

Emi ni
ALIYU IDI-OLOJA
"Tẹni begi loju"

Eko


## Akiyesi Pataki

A nfẹ Aşoju ni awọn ilu wọnyi, Otta Abẹokuta, Ibadan, Ilugun, Ololo, Agbọwa,-Iko si Ikorodu, Ọyọ, Awe, Ilesha, Ẹde, Ikirun Iwo Shaki Işẹyin, Tede, Oke-Amu, Iganna, Omu-Aran Ilorin Ajaşẹ-Ipo, Ifọ, Abalabi, Idọgọ.

Kowe si
Circulation Manager,
16, Gbamgbose Street,
Lagos.



BI O BA NI
# Iwe—Titẹ
FUN
**Lilo nibi işẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**
ATI
**IWE Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IŞẸ ERỌ—ITẸWE
**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboşe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NBGA

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Danwa wo lẹẹkanşoşo ki o si ri iyatọ*


AKIYESI

FUN IWADI, ITUMỌ ALA ATI IŞORO RẸ WA TABI KI O KỌWE SI: —WOLI ORIOLOWO AKINDELE ADEAGA COMPOUND RILE —ILUGUN VIA—IBADAN

# AKARA TU S'EPO !

## Iwe Itumọ Ala na ti de !!



Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imolẹ pe Iwe Itumọ Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade fun tita nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Odu Ifa ni nwọn fi tumọ re Egbogi jaburata si wa ninu rẹ pelu. Tete ra tirẹ ki o to tan.

J. O. SHOYINKA
N2/99 Shittu Street
Ibadan

# Awọn Ero Ọja Mu Gbọmọgbọmọ Kan

ONITSHA:— Ibosi gbọmọgbọmọ dẹ! di ọran akọlukọgba bi gbogbo ero inu ọja Onitsha ti nsare va ọmọ wọn kiri larin ọsẹ ti o kọja yi.

Ṣaju eyi, ni awọn Ọlọpa ti ṣe ikede kan wipe awọn fura si awọn kan pe, nwọn wọ ilu lati le ma a gbe ọmọ ni.

Were ni a gbọ wipe awọn ero ọja ri ọkunrin kan mu pẹlu awọn ọmọ meji ti nwọn ro pe o fẹ gbe wọn ni, ni awọn ero ọja yi ba lu ọkunrin na lalu doju Iolẹ ti o si dan mọ wọn lọwọ.

Irohin tun fi ye wa wipe gbogbo awọn obinrin ti o o wa ni ọja ni ọjọ na lo fi gbogbo iṣọ wọn silẹ ti nwọn sare lọ si ile iwe ti awọn ọmọ wọn wa lati le mu ọmọ wọn na wa sile.

Irohin awọn Ọlọpa fi ye wa wipe ọwọ awọn Ọlọpa ti tẹ enia mẹsan ti nọa si ti ti wọn mole bayi.

Nwọn si nfi ọrọ vẹ wọn lenu wo lati le mọ iru ẹsun ti nwọn yio fi kan wọn.

---

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20-Feb 18) Ọjọ oni dara fun ọ pẹlu olufẹ rẹ, gbiyanju lati bẹ awọn ọrẹ rẹ wo. Eyiyi yio jẹ anifani fun ọ lati le ri itẹsiwaju miran.

PISCES (Feb 19-March 20) Iranlọwọ nla yio de ba ọ eyiti yo le mu ọ bori awọn iṣẹ rẹ gbogbo. Ọjọ oni dara lati le ṣẹ eto fun aṣe yọri iṣẹ ti ọ fẹ dawọ le laipẹ

ARIES (March 2 -April 19) Fi iwa otitọ han gbogbo awọn ti nfẹran rẹ. Eyiyi yio mu ọ yọri gbogbo awọn ohun ti ofẹ ṣe loni.

TAURUS (April 20-May 20) Ọjọ oni dara fun ọ lati wa awọn o lufẹ rẹ ri, ṣe eto lati kọ iwe si awọn ti o wa ni o kerẹ si ọ.

GEMINI (Ma 21-June 21) Ṣe giri ki o si mura ki a arẹ ara ma ba de ba ọ. Inira diẹ yio wa larin awọn ẹbi rẹ, awọn ọrọ diẹ yio fẹ lati da ijangbọn silẹ. Adura lẹbọ.

CANCER (June 22-July 22) Ailera diẹ yio wa fun ọ nipa iṣẹ rẹ, fi eti si imọran awọn asiwaju rẹ. Orire nla yio de ba ọ lai pẹ yi.

LEO (July 23-Aug 22) Ọjọ oni yi yio dara fun ọ yio si ṣe ọ ni anifani nibi iṣẹ rẹ.

VIRGO (Aug 23-Sept 22) Ma ṣe ṣe ariyan jiyan ti yio da ija silẹ fun ọ loni. Gbẹkẹle ara rẹ fun aṣe yọri awọn ohun ti o dawọle. Ọjọ oni dara fun lati le ba awọn Ọlọla sọrọ.

LIBRA (Sept 23-Oct 23) Ọpọlọpọ ọgbọn ati oye ni yio wa fun ọ. Maṣe jẹ ki awọn atanijẹ ba ọ gbero pọ rara. Mura lati le wa alafia fun ara rẹ' ki o si gba atẹgun kakiri loni.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Iwọ yio ṣe orire nla kan lai pẹ ọjọ, ti o ba ṣe suru. Ọrọ ifẹ obinrin kan yio yọ si ọ. Maṣe jafara nipa rẹ yio dara fun ọ.

SAGITARIUS (Nov 23-Dec 21) Rogbodiyan kan yio ṣẹlẹ ni adugbo rẹ ma e sun mọ ibẹ. Eto titun miran yio tun yọ si ọ bi o ba ṣe suru.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) a ṣe ro ara rẹ pin nipa wahala ti o de ba ọ, ọjọ isinmi ferẹ de. Ṣọra nipa Obinrin kan yio sọ pe ọu ni fọ rẹ. Fi ọgbọn ba lo ki o le dara fun ọ.

---


# A TUN GBE DE!

Iwe Adura pataki fun Arisiki ati iṣẹgun lori ohun gbogbo lati ilẹ Misirat, 2/6 Adura akanṣe ati apẹrẹ ile aiye 2/- Ajọmọ-isin Ojiṣẹnla Mahammed 2/- Iwe Itumọ Ala ati Adura Ala ibanujẹ 4/6-

RANṢẸ TIRẸ SI:-
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
Idumagbo Avenue Lagos Nigeria



AH! REMEMBER THAT

# The Social Dandies

*PRESENTS*

## An Eid-Ul-Kabir Dance

AT

## FORESTER CENTENARY HALL

22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn.

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, size this opportunity and come and listen to the latest heats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E. Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprise and Bashy & His Young Stars di Orchestra. Be there in time to avoid rushing,

**Tickets: 4/- Flat**

Tikets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ Offices. Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta.



BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI-

# RICHALET

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO

Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọnmọnọ




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ọjulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati i awọn Tatambulu s Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ iba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ẹṣẹ Amodi Apo ile itọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ẹjẹ ara rẹ patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ toritoni pẹ u.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu

Waterloon Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# Ẹnyin Agbaagba E T'aiyeṣe

Lati ọwọ ARẸMU ERIN

Olotu tiwa, mojuba o, Ko dede ti emi ọmọ nyin kekere, Arẹmu Erin fi kọ akọle oke wosika mi yi si, awọn Agbaagba wa ode isisiyi bikoṣe wipe wiwo ti emi ọmọ nyin kekere nwo ode isisiyi tabi aiye isisiyi ti ṣe nlọ si yi, Olodumare jẹ ki o toro fun gbogbo wa o.

Eyi mu mi ranti orin kan ti ẹnyin baba wa ma a nkọ lẹnu igbati mo ṣẹṣẹ ngbọnju yi wipe "Ẹnyin agbaagba e tun aiye ṣe kẹ ma ma j'aiye o lọ" Njẹ aiye na ko ha nlọ bayi? Ẹnyin agbaagba na ni o tun ma a nsọ bayi wipe: "Bi ọmọde ba nge igi l'oko, agba yio ma a w'oye ibiti igi na yio ba wosi" (oṣe bi owe o).

Njẹ ko ha jẹ itiju lati gbọ wipe ki a sọ wipe bi agba ba nge igi loko, ọmọde yio ma woye ibi ti igi na yio wo si. beni ẹnyin baba wa na ni o pa a lowe bayi wipe, "Ko ni buruburu ki baba sọ wipe odi ọwọ ọmọ on lọrun" (iyẹn ṣe ewọ) ni a ngbọ tẹlẹ ri. tabi aṣipa owe ni awọn baba baba wa ṣe ni?

Papa gidi mo bere lọwọ ẹnyin agbaagba wa, bawo ni aiye na a ha ti da yi? Ko tun ṣi wipe ọrọ ọ lagbaja ni, a fi ki nwọn mu u re, ọla tabi iyi ko bajẹ lori awọn baba baba wa, e e ha tiri, e e ha ti ṣe ki o to wa jẹ wipe lori awọn baba wa ni nkan wọnyi fi nfẹ lọ bayi?

Kai! emi Arẹmu Erin wo oke mo wo'ilẹ ẹru aiye yi wa mba mi, nitori bi mo ti ṣe nwoye aiye na a si, mo ri i wipe bi o ti tọ ko tun si ni aiye yi mọ, hun u un bi o ti gba ni o ku ni aiye wa yi wa da. "Adaba jẹun ku f'ẹiyẹle, eiyẹle jẹun ku f'adiẹ, baba ni o jẹun ku f'ọmọ" la i ngbọ ri, ajẹtan lo tun ku laiye isisiyi

PUULU

Ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ ẹ jọwọ ẹ ba mi fi lakaye gbọ ọrọ kekere yi, njẹ ni ode ti oni ti a wa yi tani ko mọ wipe aiye na a le ju oju ẹja lọ.

Ko si owo tabi owo wa lọwọ rẹ, bi owo ba wa lọwọ rẹ, tabi, oto enia melo ti o mba gbe ẹru rẹ, nibiti ọmọ wa, aburo wa, iya wa, o haya ile ni, tabi ṣe iṣẹ oṣu ti nwọn ṣe nisisiyi kọ?

Ki oṣu to pari owo ti tan tabi iwọ oniṣẹ oṣu a tun ni ọna ibomiran ni. Emi ko le sọ ṣa o, boya o le riṣe ninu puulu (Pool) bi bi o ba ta puulu (Pool) ja nkọ, mo ṣe bi owo jẹun jẹun ni a fi bi Ọlọrun ba gbe orire tirẹ fun ẹ ni bẹ nikan loku.

HAGI HAGI

Paga! njẹ eyi ti owa lode oni yi ko ha to ironu fun ẹniti o moye. Ẹjọwọ ẹ wo o lati bi ọdun mẹta si mẹrin bi awọn ọmọ ile'we ti pọ lọ biba bi yanrin okun ti nwọn ko ri iṣẹ ṣe.

Mo tun fọ ki ẹgba wipe awọn ọmọ atapata dide ni ọrọ yi mba wi pupọ, ọmọ ti ojẹ wipe ki awọn obi rẹ to le ran lọ si ile ẹkọ nkan ti oju baba ati iya rẹ ri ki oto le kaa tan nkọ.

Ti ọmọ tun wa ka iwe rẹ tan ti kọ ri iṣẹ fiṣe, njẹ ironu ko di pupọ fun awọn obi ọmọ ki wa ni hagihagi awọn agbaagba wa na ti nwọn nrii wipe ọpọlọpọ awọn ọmọ wọnyi nri kakiri ti nwọn mọ nkan ti nwọn ni lati se ti nwọn ko se ti nwọn mba abosi kakiri aiye tabi nwọn ro wipe awọn maa jẹ aiye naa tan ni.

WO OJU EWE KẸFA

## Itumọ Ala

Julius Akosile Ilesha—Gbogbo oke iṣoro rẹ ni yio di pẹtẹlẹ fun ọ ti o ko ba dake adura ni ṣiṣe.

Samson Ekoolare Oke Odan—Maṣe ba ẹnikẹni da ọrọ owo, pọ laseko yi ki nwọn ma ba gbe ọ ni agbeda.

Kelani Alatishe Ifo—Ko ara rẹ ni ijanu nipa inu fufu ki o ma ba da ọran ti yio gbe ọ de ọgba onigo.

Fasasi Alaba Ikorodu—jẹki awọn Ọmọ rẹ wa ni ihamọ fun Ọjọ kanṣoṣo ki ọkan ninu wọn ma ba ṣe alabapade iku Ojiji.

Akyesi Maṣe jafara lati fi ala rẹ ranṣẹ si ni fun itumọ kikun lofẹ.

Ọgbẹni Arinrode


# Akiyesi

Ẹnikẹni ti oba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti oṣi wa laaiye tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu Itan Iṣẹdalẹ Yoruba, ki oluwarẹ kọ ọ sọwọ.

Ao si tẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ maṣe jẹki agbagbe itan Iṣẹdalẹ nitori awọn ọmọ wa.

Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU



## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"

MO JẸ KI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ

Ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMONA NIPA ISIN HAJI"

LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INAKUNA, KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA

t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Oluforijin bogbọẹda patapata" Amin.

"WAS SALAM"

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo ... oyẹ ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA

*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*

MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan



EGBOGI JAMON—:—

## 'GLUTAMONE'

TI O DABI IṢỌYE

Egbogi yi jẹ oogun pataki ti nwọn ṣẹṣẹ ṣe fun anfani awọn ti nwọn saba maa gbagbe ọrọ tabi ranti ẹkọ ti nwọn ba kọ wọn ni ile-iwe.

O tun wulo fun awọn ti iye wọn koji perepere to lati ranti awọn ohun si ọkan. Papa julọ, o dara fun awọn oniṣowo, awọn olukọ, awọn ọmọ ile-iwe ati fun agbalagba ti o fẹ dabi ẹni pe ko ni iye ninu mọ.

Egbogi yi tun wulo fun awọn "Isan ara" to o fẹ dabi ẹnipe ko mu osiri to tabi ki arẹ ma mu ni nigba gbogbo. Tabi awọn ti ima saba rẹ ti oju oroju ma nyọ lẹnu.

Egbogi yi wa lati sọ iye rẹ ji perepere ti o si ma ranti gbogbo awọn ohun ti o ti kọ fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin yio wa dabi ẹnipe o sẹṣẹ kọ wọn ni.

Egbogi yi wulo fun awọn ọmọ ile-iwe ni asiko idanwo wọn lati le mu wọn ranti gbogbo ohun ti wọn ti kọ yekeyeke.

O yẹ ki egbogi yi si a lọwọ awọn akẹkọ. Onisowo, onisẹọwọ, tọmọde tagba ni owulo fun.

Oni lowo ogun isọye ti o jẹ ti osi daju hanuhanu Bere ni sọbu awọn:-

Waterloos Mdicine Stores
8 Palmchurch Street, Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)
Adedun Chemist,
4, Wakeman Street,
Yaba.
Iṣẹ Olodumare Dispensary,
Oke-Bọla, IBADAN.

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 557 TUESDAY, MARCH 17, 1964 (2D)



## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhin ti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi yọ gbogbo enia ki o yẹ won wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni o ngbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati odun meje (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nomba

16, BAMGBOṢE STREET,
PHONE 21985, LAGOS.

OLOTU


# FAGBENRO BEYIOKU FI ẸGBẸ ALAKUKỌ SILẸ

EKO:— Oloye O. A. Fagbenro-Beyioku Ọkan ninu awọn amugbalẹgbẹ ẹgbẹ Alakukọ (N. C. N. C.) ti o si tun jẹ Ọkan ninu awọn Ọmọ Ile Igbimọ Asofin Agba Oṣelu fun Apapọ Ijọba Naijiria ti koru ninu ẹgbẹ Alakukọ ni Ọjọ Abamẹta ti iṣe Ọjọ kẹrinla Oṣu yi o si darapọ mọ ẹgbẹ Dẹmọ tuntun ti nwọn ṣẹṣẹ dasilẹ.



OLOYE BEY OKU

Oloye Fagbenro-Beyioku ti kọwe si akọweagba Apapọ ẹgbẹ Alakukọ Ọgbẹni F. S. Mcewen.

Ninu iwe ti o kọ, o ṣe alaye sibẹ wipe on ti kuro ninu ẹgbẹ Alakukọ on si ti bọ sinu ẹgbẹ Dẹmọ tuntun eyiti Oloye S. L. Akintọla alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria da silẹ.

Oloye Fagbenro—Beyioku tun ṣe a aye siwaju pe, "Mo ba parapọ di ẹgbẹ Dẹmọ yọ nitoripe mo ni igbagbọ ati ifẹkantan si Orukọ nla ẹniti o ti da iru ẹgbẹ bẹ silẹ ri, eyi ni Ọlogbe Ọlọla Herbert Macaulay.

"Mo tun ni igbagbọ inu iṣọkan ẹsọ Ọmọ Yoruba ati awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nipa w ẹgbẹ titun na Dẹmọ eyiti Orukọ rẹ nje (N. N. D. P.)

"Bakanna ni mo ni igbagbọ pe ẹgbẹ Dẹmọ yi yio tun ni anfani lẹkan si lati lo agbara re, ki iṣe ni Naijiria nikan ṣugbọn kakiri gbogbo agbaala aiye ni."

Ninu ẹ ti okọia yi ni nwọn da ẹgbẹ Dẹmọ silẹ ni Ibadan, ti gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti nwọn wa ninu ile igbimọ asofin ijọba ipinlẹ iwọ oru Naijiria si ti wọ ẹgbẹ na.

Lẹhin eyi, ti ẹgbẹ Alakukọ si wipe awọn fẹ parun tan ni Ipin Orun, ni ẹgbẹ na ba yara tete parapọ mọ ẹgbẹ Afẹnifere. Nisisyi ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre ni nwọn yio jijọ ma a ṣe Ijọba pọ ni Ibadan.

Ṣugbọn bi nwọn ẹmọ ẹgbẹ tuntun yi ba pọju ẹgbẹ mejeeji lọ, a jẹ wipe ẹgbẹ Alatako ni ẹgbẹ Alakukọ ati Afẹnifẹre yio wa.

Onirohin wa kan fi ye wa wipe Oloye Fagbenro-Beyioku nikan ni o ti darapọ mọ ẹgbẹ Dẹmọ ninu awọn ọmọ Ile-Igbimọ Agba Oṣelu.


## KERE O! AKIYESI PATAKI

Awa na le jẹri wipe Ojulowo bauhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara, Ghana) pẹlu, meji re ko si ninu gbogbo orişirişi Egbogi kakiri Ilu Naijiria.




Irohin Kakiri Igboro Ilu

Bẹ na ni ẹwẹ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti owa lẹnu bogbo enn ọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn si fi ṣe ọrọ ati orin larin ara won ni ipa Egbogi Jama i olokiki yi ti nwon npe ni LEOPILLS.

Imọran awọn Dọkita Oyinbo ti nwọn nşe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bio ti lagbara to ati o jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun awọn "JẸDIJẸDI" bi o ti wu ki ojọ rẹ pe to bere ni awọn le tun fi ọwọ soya tabi seleri fun gbogbo awọn ti amodi tabi Iju, tabi Igbẹ ṣiṣe, tabi aiko ri igbonsẹ dede, Inu rirun nigbakugba ara wiwo, Ẹsanri, ẹhin didun, Oju sisan, tabi aiko riran kedere kodoro buruku lara, Osilẹu Onigbameji ati orişirişi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe" awọn yio ri alafia ni kiakia ti awọn ba nlo Egbogi LEOPILLS nitoripe o si tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa sisọdi ọtun p t

ŞE IRANT PE ALAFIA L'OGUN ORỌ, IJAFARA SI LEWU (POSTAGE 1/9d)

IYE OWO EGBOGI LE PILLS: Igo nla sile mẹfa abọ (6/6) pere ni Igo kekere sile meta abọ (3/6) pere ni Bere Ojulowo Egbogi miran fun orişirişi Amọd ti o ba fẹ ni Şọbu awọn:-

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọna Ita Faji)


## Iyi Awa Ọmọ Yoruba Parẹ BI?

ỌPA AGBELEKA

Nwọn wa gbagbe wipe ki ato da aye, alaiye ti nse aiye, awọn tun de aiye iba ti nwọn nikan ni awọn naa yio ṣe, mo fi Oluwa bura awọn naa yio fi aiye yi şilẹ lọ ni.

Ẹba wa tun aiye yi ṣe o enyin agbaagba wa, nitori Olorun ti bu oyin si inu ẹkọ fun nyin a ma ki ọ mọ daju wipe bi ẹba ni ko ni kan ẹ yin ọpa agbeleka nkọ ṣe ẹ mọ wipe ti ẹnyin lo ṣoro.

Ẹnyin nse yala, ẹtun nṣe yolo, enyin njẹ didun, awọn ọmọ nyin sọ ọrun nu ninu moto, enyin nfa siga foo, ẹ la ọti wisiki gboo, ẹma gba gbe wipe aiye ki iṣe ti ẹnikan o, ẹ ma gbagbe kẹ tuni aiye se o.

Kẹnikan maa sanra kẹn kan maa ruu bi oba ti dara bẹ ẹ.

O digba kan na o


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboşe Street, P. O. Box 1495 Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga Yaba Lagos 17/3/64